# IṢỌKAN IJỌ

## Efesu 3:14-21; 4:1-16

## ẸKỌ 402 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Kiyesi i, o ti dara o si ti dùn to fun awọn ará lati ma jumọ gbe ni irẹpọ̀" (Orin Dafidi 133:1).**

### Kunlẹ fun Adura

Ninu Iwe ti Paulu kọ si awọn ara Efesu ni a ri akọsilẹ adura kan. Paulu gbadura fun ijọ Efesu. Gẹgẹ bi ajihinrere, Paulu ti bẹ ilu Efesu wò, o si ti ba awọn eniyan ibẹ sọrọ (Iṣe Awọn Apọsteli 18:19). Ni irin-ajo kẹta Paulu, o gbe ọdun meji ni Efesu (Iṣe Awọn Apọsteli 19:10) o n waasu fun awọn eniyan. O ni ifẹ si wọn, oun ko kọ iwe si wọn nikan ṣugbọn o gbadura fun wọn pẹlu. "Ni mo ṣe nfi ẽkun mi kunlẹ fun Baba." Eyi fi hàn iru ipo ti Paulu wà nigba ti o n gbadura. Gbogbo ọkàn rẹ ni o fi n gbadura. Lati tẹ eekun ba niwaju Ọlọrun fi irẹlẹ ati ijuba hàn. Awọn miiran ki i fẹ lati kunlẹ gbadura, ṣugbọn ibi pupọ ni a ti ri i kà ninu Bibeli nipa awọn ti o kunlẹ lati gbadura. Jesu tikalara Rẹ kunlẹ lati gbadura ninu Ọgba Gẹtsemani. Ṣaaju ki a to kan Kristi mọ agbelebu O kunlẹ, o si gbadura bayii pe "Ifẹ ti emi kọ́, bikoṣe tirẹ ni ki a ṣe" (Luku 22:41, 42).

Onipsalmu wi bayii pe, "Ẹ wá, ẹ jẹ ki a wolẹ, ki a tẹriba: ẹ jẹ ki a kunlẹ niwaju OLUWA, Ẹlẹda wa" (Orin Dafidi 95:6). Daniẹli kunlẹ lẹẹmẹta loojọ, o gbadura, o si dupẹ niwaju Ọlọrun (Daniẹli 6:10). Ki i ṣe nipa ikunlẹ nikan ni a fi le gbadura, ṣugbọn ọna ti o dara ni. Lori eekun wa, a maa n sunmọ Ọlọrun pẹkipẹki, a si n ni igbagbọ pe Ọlọrun yoo dahun adura wa. Bibeli sọ nipa akoko kan nigba ti Jesu yoo jọba lori ilẹ ayé yii ti gbogbo eekun yoo wolẹ ti gbogbo ahọ́n yoo si jẹwọ fun Ọlọrun (Romu 14:11; Isaiah 45:23).

### Agbara Ẹmi

Paulu gbadura fun awọn wọnni ti a ti gbala. Ifẹ ọkan rẹ ni pe ki gbogbo wọn le ri ọpọ ibukun gbà lọwọ Oluwa, ki wọn si le di alagbara ninu Oluwa. O gbadura pe ki wọn le di alagbara ninu "ọkunrin ti inu" – ani ẹmi eniyan. Itumọ rẹ ni pe ki wọn le jẹ alagbara ninu ẹmi. Ninu 2 Kọrinti 4:16 a ka bayi pe "Ọkunrin ti inu wa ndi titun li ojojumọ́." Nigba ti eniyan ba n fẹ di alagbara ninu ara, a maa ṣe idaraya a si maa jẹ onjẹ ti o dara. Nigba ti eniyan ba fẹ di alagbara ninu ẹmi, o ni lati jẹ́ onitara bakan naa ni jijẹ manna lati ọrun wá ni jijẹ onjẹ ti ẹmi, ati ni ṣiṣe idaraya ninu Ọrọ Ọlọrun. Nipa adura, nipa igbagbọ́, nipa kika Bibeli ati fifi ohun ti o ka ṣe odiwọn aye rẹ, oun yoo di alagbara. Ko yẹ ki eniyan jẹ alailagbara tabi oniyemeji ṣugbọn ki o maa di alagbara ninu Kristi lojoojumọ. Oluwa yoo ran an lọwọ, yoo si fun un ni ipá lati jẹ alagbara ninu Oluwa. Ọlọrun le ṣe ju bi a ti le beere, tabi bi a ti le rò lọ. A sọ fun wa pe "ero" wa tobi ju "ibeere" wa ṣugbọn "agbara" Ọlọrun tobi ju awọn mejeeji lọ.

### Ọrọ̀

Ọrọ̀ ti o wa ninu Kristi kò ni opin. Ki i ṣe wura tabi fadaka ṣugbọn ibukun iyebiye lati ọdọ Oluwa wá. "Ki Kristi ki o le mã gbé inu ọkàn nyin nipa igbagbọ." Nigba ti eniyan ba ni Jesu ninu ọkàn rẹ o ni ọrọ̀ ohun rere pupọ. Ifẹ a maa wọ inu àya nigba ti Jesu ba wọ inu ọkàn. Ifẹ yii ni o kọ́ n wọ inu ọkàn, nigba naa a o fi ibukun iyoku kun un. Nigba ti ifẹ Kristi ba wọ inu ọkàn wa, awa yoo fẹran Rẹ̀. "Awa fẹran rẹ̀ nitori on li o kọ́ fẹran wa" (1 Johannu 4:19). "Awa mọ̀ pe awa ti rekọja lati inu ikú sinu iye, nitoriti awa fẹràn awọn ará" (1 Johannu 3:14). "Nipa eyi ni gbogbo enia yio fi mọ̀ pe, ọmọ-ẹhin mi li ẹnyin iṣe, nigbati ẹnyin ba ni ifẹ si ọmọnikeji nyin" (Johannu 13:35). Ẹni ti o ba ni Jesu ninu ọkàn rẹ̀, ki i ṣe kiki Kristi ati awọn eniyan rẹ̀ ni oun yoo fẹràn, yoo fẹràn awọn aladugbo ati awọn ọta rẹ̀ pẹlu (Matteu 22:39; Luku 6:27). Abajọ ti Paulu fi wi fun awọn ara Efesu pe, ifẹ Kristi "ta imọ yọ." Kò le yé wa ṣugbọn a le ni in.

Ifẹ Jesu ni o kọ́ n wá sinu ọkàn wa lẹyin naa ni àye yoo wà fun "ẹ̀kún Ọlọrun." Oluwa ni ọpọ ibukun ni ipamọ fun awọn eniyan Rẹ̀ to bẹẹ gẹẹ ti o ṣoro lati mọ̀ bi wọn ti pọ to. Bi Ọlọrun ti n fun wọn ni ọ̀tun ibukun nikọọkan bẹẹ ni wọn n ni òye siwaju nipa ọpọ ọrọ̀ Kristi.

**Ipe Giga**

Lati jẹ́ Onigbagbọ́ ati ọmọlẹyin Kristi jẹ́ ipe giga. Paulu rán awọn ara Efesu leti lati rin yẹ si ipe naa. Paulu sọ fun awọn ara Efesu bi wọn ṣe le pa ifẹ Ọlọrun mọ́ ninu ọkàn wọn. Ọrọ Paulu ki i ṣe fun awọn ara Efesu nikan; wọn le ṣe awa pẹlu loore. Onigbagbọ ni lati rin "pẹlu irẹlẹ gbogbo ati inu tutù, pẹlu ipamọra, ẹ mã fi ifẹ farada a fun ẹnikeji nyin." Eyi le dabi ẹni pe o ṣoro lati jẹ́ Onigbagbọ́, ṣugbọn pẹlu ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn rẹ̀ Onigbagbọ yoo fẹ lati ṣe gbogbo nnkan wọnni. Ifẹ Ọlọrun ni n mu ki Onigbagbọ fẹ ṣe awọn ohun wọnni. Bi eniyan ba fi tọkantọkan fẹ Jesu, oun kò ni gbé ara rẹ̀ ga ju awọn ẹlomiran lọ -- oun yoo jẹ́ onirẹlẹ. Bi ó ba fẹran Jesu tootọ, oun ki i jà tabi ki o fẹ gba ọna ti rẹ̀ -- nitori oninututu ni i ṣe.

**Iwa Mimọ́**

"Ki ẹ si mã lakaka lati pa iṣọkan ẹmi mọ́ ni idipọ alafia." Itumọ lakaka ni lati gbiyanju ati lati ṣiṣẹ. Itumọ rẹ̀ ni pe igba miiran wà nigba ti eniyan gbọdọ ṣe aapọn lati pa iṣọkan Ẹmi mọ́. Iṣọkan jẹ́ lati wà ni irẹpọ, eyi si ni eto Ọlọrun fun awọn eniyan Rẹ̀. Jesu gbadura fun awọn ti n tọ Ọ lẹyin pe, "Ki gbogbo wọn ki o le jẹ ọ̀kan; gẹgẹ bi iwọ, Baba, ti jẹ ọ̀kan ninu mi, ati emi ninu rẹ, ki awọn pẹlu ki o le jẹ ọ̀kan ninu wa" (Johannu 17:21). "Emi ninu wọn, ati iwọ ninu mi, ki a le ṣe wọn pé li ọ̀kan; ki aiye ki o le mọ̀ pe, iwọ li o rán mi, ati pe iwọ si fẹràn wọn gẹgẹ bi iwọ ti fẹràn mi" (Johannu 17:23). Jesu gbadura pẹlu pe ki a le sọ awọn ọmọ-eyin Rẹ̀ di mimọ́ (Johannu 17:17) eyi ti yoo mu isọkan wá, ti yoo si gbà wọn kuro lọwọ ẹda Adamu. Eto Ọlọrun ni pe ki awọn Onigbagbọ ki o le dabi Kristi ki wọn si le rin "li ododo ati li iwa mimọ́" (Efesu 4:24).

Ninu Ifihan 19:8 a kà nipa awọn wọnni ti yoo wà pẹlu Jesu ni Ase-Alẹ Igbeyawo ti Ọdọ-agutan. Akopọ wọn ni iyawo Kristi, "on ni a fifun pe ki o wọ aṣọ ọgbọ wíwẹ ti o funfun gbõ: nitoripe aṣọ ọgbọ wíwẹ ni ni iṣe ododo awọn enia mimọ́." O ṣe ohun danindanin fun wa lati jẹ́ olododo ati ẹni mimọ́. Ninu 1 Peteru 1:16 a kà pe: "A ti kọ ọ pe, Ẹ jẹ mimọ́; nitoriti emi jẹ mimọ́." Ninu Heberu 12:14 a ri i pe li aisi iwa mimọ́ ko si ẹni ti yoo ri Oluwa.

**Iṣọkan**

**Paulu sọ eredi idapọ tabi isọkan yi. "Nitori ẹ̀ya-ara ọmọnikeji wa li awa iṣe" (Efesu 4:25). Paulu lo "ọ̀kan" nigba meje ninu ori iwe yii lati fi hàn bi iṣọkan awọn Onigbagbọ ti ni lati jẹ́ pipe tó. Ọlọrun kan ni ó wà. Oluwa kan ṣoṣo ni ó wà, Jesu Kristi. Ẹmi kan ni ó wà, igbagbọ kan ati baptismu kan. Ireti kan ni o wà fun gbogbo awọn ẹni irapada, ireti yii ni lati lo ayeraye pẹlu Jesu. Ara kan ni gbogbo awọn Onigbagbọ, eyi naa si ni Ijọ, ti a n pe ni ara Kristi. O jẹ́ akopọ gbogbo eniyan lati orilẹ ati ède. Akopọ gbogbo awọn ti o gbagbọ́, Ju ati Keferi, ni a n pè ni Ijọ. A fi wé "apapọ ẹbi kan."**

**Ẹbun**

Fun olukuluku ẹni ti o wà ninu ẹbi Ọlọrun ni a fun ni ẹ̀bun kan tabi talẹnti. Ki i ṣe gbogbo wọn ni o le kọrin bakan naa. Gbogbo eniyan kọ́ ni o le waasu, "ṣugbọn olukuluku wa li a fi ore-ọfẹ fun gẹgẹ bi oṣuwọn ẹ̀bun Kristi." Olukuluku ni yoo jihin fun Ọlọrun iru ọna ti o lo ẹ̀bun ti a fi fun un sí. Awọn miiran le fẹ ṣe iṣẹ ti a fun ẹlomiran, ṣugbọn olukuluku wa ni lati ṣe iṣẹ ti a fi le wa lọwọ. Wo bi yoo ti mú rudurudu wá bi olukuluku wa ba dide lẹsẹ-kan-naa lati waasu! Kò ni si ijọ ti yoo fetisi iwaasu. Alufaa le ju ẹyọ kan lọ ninu ile Ọlọrun ṣugbọn olukuluku wọn ni iṣẹ ti rẹ̀ lati ṣe. "Ọlọrun ki i ṣe Ọlọrun ohun rudurudu, ṣugbọn ti alafia, gẹgẹ bi o ti jẹ ninu gbogbo ijọ enia mimọ́" (1 Kọrinti 14:33).

**Ara Kan**

Bi olukuluku ba si ti n ṣe ipa ti rẹ̀, idagbasoke yoo wà ninu Kristi, a o si maa dabi Rẹ̀, Ẹni ti i ṣe Ori wa. A le fi Ijọ Ọlọrun wé ara kan. Ilò wa fun ọwọ́ ati ẹsẹ̀; bakan naa ni ninu ara Kristi, a ni lati ni awọn akọrin, olukọ, alufaa, ati awọn ajihinrere. Olukuluku ni lati fi ọkan otitọ sa ipa ti rẹ̀ lati mu aṣepọ ara kan wà, ani "ọkunrin pipe." Ro bi yoo ti ri bi ọwọ́ ba pinnu lati ṣe iṣẹ ti ẹsẹ̀ n ṣe! Bakan naa ni o ri nigba ti ẹni kan ba n gbidanwo lati ṣe iṣẹ ti a ti fun ẹlomiran lati ṣe. Ro bi yoo ti mu iṣoro lọwọ to bi ẹsẹ̀ kan ba n gba ọna kan ti ẹsẹ̀ keji bi n gba ọna miiran. Bakan naa ni o ri nigba ti gbogbo wa ko ba ṣiṣẹ ni

iṣọkan ati ifẹ. Ọlọrun ti mu ki o ṣe e ṣe fun gbogbo wa lati gbe pọ̀ ki a si le ṣiṣẹ pọ ni irẹpọ, nigba ti a ba ni ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn wa ti a si ti sọ wa di mimọ́ patapata, nigba ti a ba gbẹkẹle Ọlọrun ti a gbọran si Ọrọ Rẹ̀. Apapọ gbogbo wa ni o di ara kan ninu Kristi – "ara na ti a nso ṣọkan pọ."

**AWỌN IBEERE**

1 Iṣẹ itankalẹ ihinrere wo si Efesu ni a n kẹkọọ nipa rẹ̀ ninu ẹkọ yii?

2 Bawo ni a ṣe mọ pe Paulu kunlẹ lati gbadura fun Ijọ?

3 Darukọ diẹ ninu awọn eniyan ti a kà nipa rẹ̀ ninu Bibeli ti o kunlẹ lati gbadura.

4 Ki ni eniyan le ṣe lati dagba ninu ẹmi?

5 Ki ni ṣe ti a ṣe ni lati dagba ninu ẹmi?

6 Sọ ibi meje ninu ẹkọ yii nibi ti Paulu ti lo ọ̀rọ yii "ọ̀kan."

7 Sọ awọn ẹsẹ miiran ninu Bibeli ti o sọ nipa iwa mimọ́.

8 Bawo ni a ṣe fi Ijọ wé ara Kristi?

9 Ki ni iṣọkan?

10 Bawo ni awọn eniyan ṣe le ni iṣọkan?